# ỌRỌ-OLOTU

## IMỌRAN FUN AWỌN ARA EKO

NINU iwe wa ọsẹ ti o kọja yi, ti ojọ kẹrinlelogun osu kejọ odun yi ẹnyin onkawe wa ẹ o ti ri i ka pe Oba Eko ko ni ẹtọ ko si ni aṣẹ lati rọ Ijoye rẹ loye tabi lati fi ẹniti o ba wu u jẹ oye. Alhadji Muhammadu Ribadu, Minista Alamojuto Ọran Ilu Eko, Isura Ilẹ ati Agbara ṣe alaye yekeyeke nipa ọran na, o ni o lodi si ofin ati aṣa iṣẹdalẹ Eko fun Oba ki o ma a se ohunkohun ti o ba wu lori awọn Ijoye rẹ. Alaye rẹ ti o ṣe yi tẹ wa lorun pupọ, nitori bi ọran na ti ri gan an ni o so, ko fi bopo-boyọ, a si dupẹ fun un.

A FẸ ki Ọba Eko ma a lo ifẹ ododo si gbogbo awọn Ijoye rẹ, paapa si awọn Olori wọn, awọn bi Olumẹgbọn -Ajaye, Obanikoro-Abẹbejoye, de aye ti yio fi ran gbogbo wọn lowọ ti nwọn yio fi ma a gba owo ifẹhinti loṣoosu lọdọ Apapọ Ijọba Naijiria gẹgẹbi on na ti ṣe ngba a; nitoripe gbogbo wọn ni nwọn ni ifẹ ododo si i nwọn si fi i han an 'gbati o fẹ gun ori oye. Bukata awọn Ijoye Eko pọju. Nwọn ni ẹtọ lati ma a gba owo ifẹhinti, nwọn si gbọdọ ma a gba a.

A dupẹ gidigidi lowo Ẹgbẹ Afẹnifẹre fun oore nlanla ti awọn idile ẹbi Ọba, orẹ Ọba, Ijoye ati awọn ọmọ Eko ko le gbagbe lailai, ti o ṣe fun Ọba. Ẹgbẹ na ni o ṣe atilẹhin fun un, pẹlu Ogo Oluwa, ti o fi ngba ẹgbẹsan ponun (£1,800) owo ifẹhinti lọdọọdun: eyiyi nipe, o ngba adọjọ ponun (£150) loṣoosu dipo ponun mẹdọgbọn (£25) ti o ti ngba ri loṣoosu.

Nigbati Oba ngba owo gọbọi yi, kinise ti ko fi le ṣe atilẹhin fun awọn Ijoye rẹ de aye ti nwọn yio fi ma a gba owo ifẹhinti? Kinise ti ko fi wa iranwọ fun wọn lọdọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre, oloore rẹ? Baalẹ tabi baale ilu kan gbọdọ ma a ṣe iranwọ gan an fun awọn ọmọ rẹ ni, o gbọdọ ma a dun wọn ninu. Nipabayi on na yio ma a gbadun wọn, awọn na yio si ma a gbadun rẹ. Baale ti o ba mọ ti ara rẹ nikan ki i niyi. Abun ki i jẹ "Adeniyi".

"Bi a ko ba ṣe fun ilẹ a ki i f'owọ sọ ọ". Ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe iṣẹ ribiribi fun Ọba Eko, o gbe e ga. "Adegboyega" ni Ẹgbẹ Afẹnifẹre njẹ: ẹgbẹ na n'o ṣe atilẹhin fun un de aye ti o fi wa laye Baba Isalẹ Igbimọ Ijọba Ibilẹ Eko. Ọmọ eni ti a ba ṣe obi rẹ ni oore gbọdọ dupẹ fun oloore obi rẹ na ni. Ẹniti o ba si dupẹ oore ana yio ri omiran gba si.

Ki ẹnyin Ijoye Eko ba a le ma a gba owo ifẹhinti ki ẹ ba a le ma a fi igbadun ṣe ayọ, ki ẹnyin ọmọ-Ọba Eko, ọmọ Ijoye Eko, ẹnyin ọmọ Ibilẹ Eko ati ẹnyin ara Eko jake-jado ba a le fihan pe, ẹ ki iṣe abaramọrẹjẹ, ki ẹ ba a le ni owo pupọ ati alafia, ẹ ronujinlẹ, ẹ parapọ dibo fun Ẹgbẹ Ọlọpẹ, Ọpẹ ti iṣe Igi-owo, wọ Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria.

# ORIN MIMỌ TI A FẸRAN

### Lati Ọwọ E. Alabi Thompson

"SUGBỌN tali emi, ati kili awọn enia mi ti a fi le ṣe iranlọwọ tinutinu bi iru eyi? Nitori ohun gbogbo ọdọ rẹ ni o ti wa, ati ninu ọwọ rẹ li awa ti fi fun ọ."—I Kronika 29 ẹsẹ 14.

1. Oluwa ọrun on aiye
Wọ n'iyin at'ọpẹ yẹ fun
Bawo l'aba ti fẹ Ọ tọ.
Ibu Ọrẹ.

2. Fun ara lile wa gbogbo
Fun gbogbo ibukun aiye
Awa ṣọpẹ, a si nyin Ọ
Ibu Ọrẹ.

3. Fun idariji ẹṣẹ wa
Ati fun ireti ọrun
Kil'ohun t' aba fi-fun Ọ
Ibu Ọrẹ.

4. Ohun t'a bun Ọ Oluwa
Wo o san le pada fun wa
L'ayọ l'a o ta Ọ l'ọrẹ
Ibu Ọrẹ.

5. Iwọ t'a t'ọdọ Rẹ dide
T'awa t'ẹbun on ini wa
Jẹk'a le ba Ọ gbe titi
Ibu Ọrẹ.

### ITAN ORIN NA

Orin yi jẹ ọkan ninu orin Ọjọgbọn "Williams Wordsworth" eyiti o kọ lati fi iyin, ogo ati ọla Ọlọrun han, paapa nipa iṣẹda aiye ati anu Ọlọrun ti o yi wa ka, orin yi jẹ ọkan ti a fẹran lati ma a kọ ni pataki nigba Ajọdun Ikore.










Ti o ba nlo ọṣẹ atawọṣe Lux fun iboju, ki iṣe pe o bọ ju lasan ni, o nṣe oogun—atẹwaṣe funra rẹ ni pẹlu.

Ti ifofo ọṣẹ atawọṣe Lux ti o kunna mulọ-mulọ ba wa ni oju ati ọrun rẹ—wa a mọọ lara gẹgẹbi ori-amọ lẹsẹkẹsẹ. Fi sibẹ fun igba kinun nigbana ki o wa fi omi ṣan gbogbo ifofo ọṣẹ na kuro, ri i pe o ṣan an mo ki o wa fi aṣọ—inura nu oju rẹ ki o gbẹ.

Lẹsẹkẹsẹ awọ-ara rẹ yio bẹrẹsi mọ iyatọ—yio si tubọ ma a dan si i yio si tutu. Abajọ ti awọn arẹwa obirin Naijiria fi nlo ọṣẹ atawọṣe "LUX TOILET SOAP!"

*Ẹnyin paapa le tubọ rẹwa si i ti ẹ ba nlo ọṣẹ atawọṣe "LUX TOILET SOAP"*




# Iwasu Evangelist Akande lori Oke-Ajodun

AGELU JERUSALEMU.

NIGBATI nwon pe Evangelist J. J. Akande, Ogbomosho ni ojo keji ti nwon ti gun ori Oke-Ajodun nse ni gbogbo enia yombo re ti nwon si kigbe Alleluyah! Onifoto si dide lesekese o ya foto re ki o to gori aga iwasu. Nitori gbogbo awon enia ni o ti mo Akande bi o ti se nfi Imole Ihinrere Jesu gbogun ti awon alaigbagbo ati onise-okunkun yika gbogbo ilu Naijiria.

Ajanaku kuro ni mo ri eranko kan ni igbe firi, Oba ni erin je ninu awon eranko. Be e gan an ni ti Evangelist Akande Ogbomosho je larin awon Ajihinrere. O gun ori aga iwasu na ni deede ago kan abo osan, o si ki olukuluku omo Egbe Kerubu ati Serafu ti o wa si Ajodun na. Gbogbo awon enia si paroro lati fi eti si iwasu re. O ni on ko ni ise iwasu gigun nitoripe akoko nlo.

O yan opolopo ese wura lati inu Bibeli fun iwasu re ti o si je pe gbogbo ese wura na ni o se alaye won ni kikun pe obun ti o mu ki olukuluku awon ese wura wonyi fi waiye ni pe ki o je arikogbon fun gbogbo awon onigbagbo. Ninu awon ese wura re na ti o yan ni Orin Dafidi 66: 8-9; Matteu 7: 21. Korinti Keji lati ese kini de ipari ati Eksodu 14: 14. Bi o ti nse alaye ati itan awon ese wura re na lesekese ni Akowe Ijo Woli S. A. Abegunde nko won sile letoleto.

O se ikilo fun awon Ojise-Olorun pe ki nwon sora gidigidi, ki nwon mase gbe oju le e pe, nipa imo won ni Olorun se yan won si aye na, sugbon Oluwa yan won lati se ise igbala larin awon elegbe won, lati ma a to won si ona ti nwon yio fi mo On Olorun ni, ati lati fi ife-inurere han si gbogbo orile-ede gegebi ase ti Jesu Kristi ti fi le awon lowo.

O si tun se alaye fun gbogbo Ijo pe, nitoto ni Olorun ni ife si gbogbo orile-ede bakanna, sugbon nipa iwa ati isesi onikaluku ni Olorun fi nyan ayanfe Re larin won, ati nipa iwa aibikita awon miran ni nwon fi nja ara won kuro lodo Olorun. Nipa bayi, o so itan okunrin kan ti o ni iyawo meta ati iwa ti iyawo-ikehin won nhu si oko won, ki oko won to yan an ni aayo-obirin.

Iwasu re na dun mo gbogbo awon ti o pejo si Oke Oluwa na bi i ki o ma dake mo ni. Gbogbo okan ti o gbo iwasu na ni o nkansaara si i, ti nwon si ngbadura fun un. Nigbati nwon sokale lori Oke na ni ojo keta ni nwon se ifilo ere Egbe Imole ti nwon i ma a se lododun nigbati nwon ba sokale lati ori-Oke Ajodun na. Evangelist Akande, Ogbomosho ni nwon si yan ni Alaga ere-Ajodun na.

# Isubu se mba Egbe Alakuko

ADO-EKITI.

NI ojo 'Ru ti ise ojo kokandinlogun osu yi ni Ogbeni Francis Adu, omo Egbe Afenifere (Action Group) segun Ogbeni Michael Ogunyemi, omo Egbe Alakuko (NCNC) ninu ibo ti nwon di ni adugbo "A" ilu Odo-Ado, Ekun Ekiti gegebi asoju adugbo na wole Ile Igbimo Ijoba Ibile Ado-Ekiti. Oodun ibo o le mokanla (311) ni omo Egbe Afenifere gba, omo Egbe Alakuko si gba igba o le mejo (208) pere.

Ogbeni S. A. George Akowe Eto Egbe Afenifere fun Ekiti so pe isegun ti awon ni lori Egbe Alakuko yi fihan gbangba pe isubu ti duro de Egbe Alakuko ni ilu yi ati agbegbe re ninu idibo fun awon asoju egbe na lati lo si ile Igbimo Apapo Ijoba Naijiria ti nwon yio di ninu osu kejila odun yi.

# Aworan Iwuye Oba Ojuwoye, Mushin



Aworan oke yi ni ti igbati Ogbeni Jinodu Ajibore lo ri Oba Alafyeluwa Jimo Aileru, ni Ojuwoye, Mushin ni asiri lehin igbati Oba na ti jo gbedu, ti o si kanse yika gbogbo awon ojubo-isese awon baba-nla re tan ni ojo ti o nse inawo iwuye Oba ti o je na ni ojo Abameta ti ise ojo kejilelogun osu yi. Alhaji S. O. Gbadamosi ni o mbo Oba na lowo ti o si nki i ku ori-re ninu aworan isale yi.

# Odaran kan ni eniti o mba on sejo sebi on nfe on lobirin ni

IJEBU-ODE.

NI ojo Ojobo ti ise ogunjo osu kejo odun yi ni Adajo Kotu Ijoba Ibile Ijebu-Ode tim ju odaran kan, Phillip Obetun, eni odun merindinlogbon, ti awon olopa pe ni onibara awon, ti o sa jade kuro logba ewon nibiti o gbe nsinru ewon odun meta fun esun pe o sa jade kuro ninu itimole Ijoba, si ewon odun meji miran nitoripe, o pe ara re ni olopa.

Ejo ti olopa ti o mba a sejo ro ni pe, odaran na pe ara re ni olopa fun Ogbeni kan, Peter Ewedo, ati pe on wa lati tu ile re wo ni. Nigbati Ogbeni Ewedo si bere fun iwe-ase ti o gba lati tu ile na wo ti ko si le mu u jade ni o ba pe olopa mu u.

Ejo ti odaran na ro ni pe, Ogbeni Ewedo ni o fan se pe on wa si ile re ni o ba fi da on duro sibe; nitoripe o sebi on ni okolokoji re.

Se ohun to wa nigba
NI PA GIGUN KEKE OLOGERE
Move with the times —ON A CYCLE
Awon enia to nte iwaju lo ngun Basikulu
RALEIGH
TI A FI OGEDE IRIN TUTU SE

## CLASSIFIED ADVERTISEMENTS

### FUN TITA

IWE Ilo agbara Psalmu 7s. 6d., Iwe Adura ojojumo 5s. 6d., Iwe Ifa ati ti Isewiwo 12s. 6d., Ajo-itaja 30s., Turari-itaja 10s. 6d., Ajo Orire £3. Kowe fun Iwe-itaja si MANAGER Box 104, Ebute Metta, Nigeria.

### A TUN GBE DE

VOCABULARY Akomolede Ede Hausa ati Oyinbo dapo mo Yoruba 2s. 6d., Adura pataki fun igbesi aiye alafia 2s, Atumo Ala ati Adura 4s. 6d., Kurani Esu mewa lede Yoruba 10s., Iwe Egbogi Iwosan atiaiyebaye to kun fun Ifa ati Itose ninu Odu Merindinlogun 10s. 6d. Postage 1s. Fi owo ranse si EBAN KOOBOGUN SERVICE, 8 Idumagbo Avenue, Lagos, Nigeria.

### FUN IBANIKEDUN

SI enyin ore, olufe ati omoleh ni Ogbomosho, Eko, Ibadan, Oyo, Ghana ati Ilorin mo ki nyin fun Ibanikedun ati fun Inawo nara nyin ti omode mi Eyitayo Awolola to fi aiye sile ni ojo Jimo 14th August 1959. Oluwa ko ma jeki nfi iru eyi san fun nyin, Oluwa na ko da awon omode onikaluku si fun rere o. E ku Idide o. ABRAHAM OKUNADE AWOLOLA.



Oloye Akitoye Coker, Aṣoju titun Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ni ilu Oyinbo ni o mba Margaret Hamilton, Akọwe Ile-iṣẹ na tẹlẹri sọrọ ni ibi ase apejẹ idagbere ti Oloye M. S. Ṣowọle ti o ti wa ni aye Aṣoju Ipinlẹ na ri pe nigbati o gba isimi kuro lẹnu iṣẹ pada bọ wa si Naijiria.

# Ogunnaike ṣe ikilọ fun awọn Adajọ Ijọba Ibilẹ

BADAGRY.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kerindinlọgbọn oṣu yi ni Ọgbẹni J. S. O. Ogunnaike, Alaga awọn Igbimọ Iṣẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria (Chairman Western Nigeria Local Government Service Board) tẹnumọ fun awọn ọgbọn (30) Adajọ Kotu Ibilẹ Ipinlẹ Iwọ-Orun ti nwọn wa si Badagry fun ẹkọ lori iṣẹ wọn pe ki nwọn maṣe ṣegbe tabi ojusaju ninu iṣẹ wọn, ki nwọn maṣe ni ọwọ ninu ọran iṣelu, ki nwọn ma a ṣe ododo ninu iṣẹ wọn nigbagbogbo fun igbega, iyi ati igberaga ilu Naijiria.

Ọgbẹni Ogunnaike fihan ninu imọran ati ikilọ rẹ pe, "Iwa rere ni ẹṣọ enia." O ni nitori iwa ọmọluwabi ti awọn Adajọ na ni Ijọba ti ṣe yan olukuluku wọn, gẹgẹbi o ti tọ ati bi o ti yẹ, si aye onidajọ ododo lati le ma a ṣe iṣẹ na ni ọna ẹtọ fun anfani ilu wọn. Ni ipari ọrọ rẹ, o ni awọn Igbimọ on ti ṣe e ni ọranyan lati ma a ṣe iwadi awọn ẹsun ti awọn ara ilu ba mu wa si ọdọ wọn nipa awọn onidajọ.

## Ọdaran apania kan ni: "Nitoripe o korira mi ni mo ṣe ṣa a pa"

EPẸ.

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kokandinlogun oṣu yi ni ọdaran apania kan ti oruko rẹ njẹ Fasasi Bello ti awọn ọlọpa mba ro ẹjọ pe on ni o pa arakunrin rẹ kan ti o njẹ Otuberu Balẹ nitori ede-aiyede kan ti o wa larin wọn sọ niwaju adajọ Kotu kekere kan ni ilu yi pe, "ologbe na korira mi pupọ, ko si jẹki awọn ọmọ rẹ jẹ iṣẹ fun mi nigbati ara mi ko ya" ni on ṣe ṣa a pa nigbati on gbadun dara-dara.

Awọn ọlọpa ni nigbati ọdaran apania na ri i wipe on pa ọkunrin na tan ni on paapa ba gbe ọbẹ le ara rẹ ni gogongo, o ṣubu lulẹ lẹba ologbe na, ọbẹ na si wa l'ẹgbẹ rẹ, ni nwọn ba sare gbe ọdaran na lọ si ile-iwosan fun itọju, nigbati ara rẹ si ya daradara ni awọn ba mu ẹsun rẹ yi wa siwaju adajọ. Bi a ba ti gbọ irohin ipari ẹjọ na si ẹ o ma a gbọ o.

## Oluko Agba kan ni eto Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun peye

ỌYỌ

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni awọn obi ati oluko awọn ọmọ ile-iwe "Anglican Methodist Secondary Modern School" ṣe ipade kan ni gbọngan ile-iwe wọn. Ninu ipade na ni Ọgbẹni E. D. Giwa, oluko agba ti sọ pe, Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni awọn eto atata fun awọn ti o ba ti ka iwe jade ni "Secondary Modern School". O ni lẹhinti awọn Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti fi ẹdẹgbẹsan pọnun (£1,700) ṣe atilẹhin fun awọn ile-iwe wọn tan lati fi kọ ile-iṣẹ "Domestic Science" nwọn si ti tun fẹ fi owo miran ṣe atilẹhin fun awọn ile wọn na lati fi ra awọn iwe oriṣiriṣi ti o dara sibẹ fun anfani awọn ọmọ ile-iwe na ati awọn oluko wọn paapa.

## Alhaji Oshishi ti Mẹkka de

EKO.

LỌNULỌLỌYI ni Alhaji Tairu K. Oshishi ti Mẹkka ati Mẹdina nibiti o gbe lọ jọsin fun Ọlọrun de. Awọn ẹbi rẹ ati Ẹgbẹ "Zumratu Islamiyyal" ati awọn ọmọ ile-iwe ẹgbẹ na ati ọpọlọpọ awọn gbajumọ Eko, l'ọkunrin l'obirin, nwọn le ni ẹgbẹẹdogbon (5,000) enia ni nwọn lọ pade rẹ ni Iddo. Nibẹ ni ọkan ninu awọn ẹbi rẹ ti fa eṣin



Alhaji T. K. Oshishi

* * *

nla kan ti o gun lọ si Mọṣalaṣi Jimọ le e lọwọ.

Awọn Imam-Deen, Alhujaj ati Alfa ṣe akanṣe isin idupẹ fun Alhaji titun na ninu mọṣalaṣi na. Nigbati o dariwale, awọn aya ati ẹbi rẹ si fi oriṣiriṣi jijẹ tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọlọ na lọrun titi ilẹ fi ṣu.

Alhaji Oshishi, o ku ori ire.

## Enia mejilelọgbọn ku ninu jamba ọkọ-ofurufu

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kokandinlogun oṣu yi ni ọkọ-ofurufu awọn Gẹẹsi kan ti o njẹ Dakota kọlu ṣonṣo ori oke-giga firofiro kan ni ẹba ilu Spain, ọkọ na si fọ, o tuka yanyan kakiri lori ilẹ, gbogbo awọn enia mokandinlọgbọn ti ọjọ ori wọn bẹrẹ lati ọmọ ọdun mọkandinlogun ti ọkọ na nko lọ padanu ẹmi wọn. Awọn mẹta ti nwọn jẹ oṣiṣẹ ninu ọkọ na paapa ku pẹlu, aropọ awọn ti o ku na jẹ mejilelọgbọn.

L'ọwọ iku ojiji Oluwa rere gba wa.



Ninu aworan oke yi, ẹ o ri i bi awọn Woli Obirin Ijọ Kerubu ati Serafu ti ngbadura ti nwọn si mbẹ Ọlọrun tẹdu-tẹdun ọkan pe, ki O jọwọ yi ọkan Ijọba Faranse pada kuro ninu ero wọn ti nwọn ngba lati dan ọta afọnja-oloro (bombu) wo ninu Aṣalẹ Sahara.




# Akiyesi awọn Awo-Irawọ nipa Ọjọ-Ibi

AWỌN nkan wọnyi ni yio ṣẹlẹ larin ọsẹ yi lati August 30th si September 5th, 1959.

## CAPRICORN

(Dec. 21st-Jan 19th)

O ni awọn iwe pupọ lati kọ ninu ọsẹ yi, boya wa a fi ọwọ si iwe adehun pataki kan. Bi o ba ngbero eto-ẹkọ pupọ lati kọ tabi lati rin irin-ajo ti o jinna pupọ, akoko to nisisiyi lati dide si sise rẹ. Ọkan rẹ yio balẹ pupọ ni ipari ọsẹ yi ju eyiti o ti ngbadun rẹ ri lọ.

## AQUARIUS

(Jan. 20th-Feb. 18th)

Iyọnu airowolọwọ wa fun ẹ gan an ni aṣeko yi. Ki o to dawọle ohun pataki ti o lẹ gba ẹ ni asiko pupọ lati ṣe, ri ohun ti o fẹ ṣe na daju. Yala o fẹ imọran yi tabi o ko fẹ ẹ, o ni lati wa alejo kan kun ara rẹ fun aṣiri ara rẹ ati ifaiyabalẹ rẹ.

## PISCES

(Feb. 19th-Mar. 20th.)

Ọsẹ yi gbadun pupọ bioba̧ṣepe o ngbero lati tọrọ iyawo ni. O si tun ṣe pataki fun ifọwọsowọ siṣe ati idapo titun ninu ohunkohun. Fi ọkan si i pe, ẹkun-rẹrẹ ere owo fun ohun ti o nse lọwọ nisisiyi yio falẹ titi di osu kọkanla ọdun yi.

## ARIES

(March 21st-Apl. 20th)

O le ṣe atunṣe ọna iṣẹ rẹ, o si le tun ri ọna iṣẹ titun miran Bi o ba ri i wipe iṣẹ rẹ titun na mu ọ ṣe alabapade alagba kan, o fi ndara ni. Nkan ajumọṣe a ma a mu igbokegbodo wa. Ma fi omugọ ṣe ileri.

## TAURUS

(Apl. 21st-May 20th.)

Yọtọmi ni o wa ninu ọsẹ yi. Ifẹ olufẹ ti o ro pe o ti ku ti tun waye, tabi ki o tun ri atunji igbadun aiye rẹ. Ọsẹ yi tilẹ gbadun pupọ fun irin-ajo tabi ki o fi gbatẹgun lọ fun isinmi.

## GEMINI

(May 21st-June 20th)

Bi o ba nwa ile gbigbe, jẹki o di arin ọsẹ yi ki o to mura si wiwa rẹ. Laiṣe ani-ani, ijongbọn ọmọlẹbi kan wa nilẹ ti o nfe yẹra fun. Nipa ti ọna iṣẹ, igbega ati arisiki owo pupọ wa fun ọ ni aṣeko yi.

## CANCER

(June 21st-July 20th)

Wa a ri itẹlọrun ati ifaiyabalẹ ni ipari irin-ajo yi. Akoko yi gan an ni o fi le tun ọna rẹ ṣe lọdọ olufẹ rẹ alijọ ki o si ṣeto fun igbeyawo bi o ba yẹ bẹ ẹ tabi ki o mu ọna igbesi-aiye titun pọn bi o ba fidi joko tan. Nipa ti arisiki owo, ko ni iyanju taara ninu ọsẹ yi. ṣugbọn yio dara fun ọ ju bi o ti lero lọ.

## LEO

(July 21st-Aug. 21st).

Wa a lo akoko pupọ lori ero pe bawo ni wa a ti ṣe ri owo ninu ọsẹ yi. O ni lati tete ṣe eto lori boya nipa ọmọlẹbi tabi nipa ile kan. Ma jafara lati ṣe iyipada nipa nkan agbiyele rẹ ki o si mọ ọna ti o ngba ni ojojumọ.

## VIRGO

(Aug. 22nd-Sept. 22nd)

O nṣe royi-royi ọkan nipa ẹwun-ọkan kan eyi ti ko dun mọ iyawo rẹ tabi ti yio gbun agbiyele rẹ. Fi ibaralẹ ronu dada,niwọn igbati o jẹ wipe, ohun ti o ba ṣe nisisiyi yio wa pẹlu rẹ fun ọjọ pipẹ. Maṣe fetisi ibawi ati ikanra, ṣa tẹle imọran ti ọkan rẹ ti o dara.

## LIBRA

(Sept. 23rd-Oct. 23rd)

Ọsẹ eto siṣe ni ọsẹ yi, ki iṣe ti iṣẹ. Biotilẹjẹpe, ọkan rẹ daru o si ndaamu, ọna ko ti i le la fun ọ titi di ẹhin ọjọ ọjọ'bi rẹ. Fun igba diẹ, ma a wadi ohun ti awọn alagba ninu ẹbi rẹ ngbalero.

## SCORPIO

(Oct. 24th-Nov. 22nd)

Wa a ṣe alabapade ẹni-atijọ kan, akọkọ nipa iwe kikọ lẹhinna nipa ipade. Isọji ti alabapade yi dabi ohun ti ọ le mu iyipada ba ọ ni ọjọ iwaju. Bio ba si di ipari ọsẹ ohun ti o ti ndaniyan lati ọjọ pipe yio sunmọ itosi rẹ.

## SAGITTARIUS

(Nov. 23rd-Dec. 20th)

Wa a ṣe eto kan tabi fowosi iwe adehun kan ni ibẹrẹ ọsẹ yi, eyi ti yio gba ọ ni asiko titi jale ọdun yi. Biotilẹjẹpe owo ko wọle kiakia, anfani rẹ yio ma a gberu siwaju lojojumọ. Ọsẹ yi dara fun siṣe alejo ati fun ẹgbẹ gbajumọ sise.





PHILIPS

'West African' RECORDS

Wholesale Distributors:

Badejo Stores, 5 Olorogun St., Lagos
Dayo Development Co., 161 Victoria St., Lagos
Jony Ola Fajumolu & Bros., 21 Balogun St. West, Lagos
Nwosu Bros. Stores, 24 Asa Rd., Aba
Ebele Egbunam Stores, 38 Church Road, Kano
Olasinbob Business Enterprise, P.O. Box 53, Kano
Ezenwenku Trading Stores, 48 Aggrey Road, Port Harcourt.

PHILIPS (W.A.) LTD. P.M.B. 2023 Lagos



Iwọ yio ri
i pe ẹwu
rẹ L'OMỌ JU
OMO Lofi
fọ ọ



Wo iyatọ larin awọn ẹwu mejeji yi—bẹ ẹ nwọn sẹṣẹ fọ awọn mejeji tan ni! Eyi ti nwọn fọ ninu Omo ni o mọ ti o si tan—O mọ gara to bẹ ẹ gẹ.

Gbogbo awọn ẹwu nyin olorisirisi awọ ati funfun ni yio si mọ dada ti yio si ma a tan ti o ba fọ wọn ninu Omo.

OMO ni o nfọ aṣọ
mọ julọ ni gbogbo
agbaiye!



